# IROHIN IMOLE

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 606 SATURDAY MAY 16, 1964 (2D)


## Awọn Ole So Onile Mọ Ori Igi

ABAKALIKI:— Idaamu nla ba gbogbo enia nigbati awọn ọlọṣa kan gbe moto ayọkẹlẹ kan de ni arin oru ni Akwa, ilu kan ni agbegbe Abakaliki ni Ipinlẹ Ila Orun Naijiria ti nwọn si fẹ ko ile itaja Ọgbẹni Martins ati Nnaji, ṣugbọn nigbati nwọn ko gba, ni awọn ọlọṣa na ba fi ipa so Nnaji mọ ori igi aja, nigbati ariwo rẹ pọ ti gbogbo awọn aladugbo fẹrẹ ji ni nwọn ba gbe Martins sinu moto wọn pẹlu ipa ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kejila oṣu yi.

Irohin fi ye wa pe ariwo enile ti nwọn so mọ oke aja ni o ji gbogbo enia larin oru. Nigbati awọn enia na ji ni Ọgbẹni S. U. Nwele, ti iṣe ọmọ Ile Igbimọ Aṣofin Ipinlẹ Ila Orun ti o wa ni adugbo na ba gbe moto rẹ jade larin oru pẹlu enia mẹrin ni inu pẹlu rẹ, nwọn ko rin ju ibusọ marun lọ ti nwọn fi ri moto awọn ọlọṣa na ni ọkankan.

Nigbati o ku diẹ ki nwọn ba moto na, ni nwọn ba yinbọn si taya mọto na mọto na ko si le lọ mọ, ni awọn ọlọṣa na ba sare jade ninu moto na, nwọn fi moto wọn silẹ, ṣugbọn awọn enia na jade ninu moto wọn nwọn si nle awọn ole na lọ, awọn ọlọṣa na yinbọn ṣugbọn ko ba awọn enia na.

Lẹsẹkẹsẹ ni nwọn mu meji ninu awọn ọlọṣa na ṣugbọn awọn yoku salọ. Irohin fi ye wa pe aṣọ awọn Ọlọpa ni awọn ọlọṣa na wọ nigbati awọn ti nlọ ṣe iṣẹ ibi na.

Awọn enia na ti mu awọn ọlọṣa na lọ si Tẹṣan Ọlọpa, nwọn si ti lọ gbe moto Takisi ti nwọn fi nkole kiri larin oru, nwọn si nwa awọn yoku wọn lọwọ.

# AWỌN ỌMỌ ẸGBẸ AFẸNIFẸRE MẸRIN JARE ẸJỌ !!

EKO:— Gudugbẹ ja ! ariwo ayọ nla si ta gee, kakiri gbogbo ilu Eko ati yika igun mẹrẹrin ilẹ Naijiria titi de Oke-Okun pe, Ile-ẹjọ gigajulọ fun Orilẹ-ede Naijiria ti ngbọ ẹjọ Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ. Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre, ti da awọn Ọmọ ẹgbẹ na mẹrin silẹ ni Owurọ ana Ọjọ Ẹti ti iṣe Ọjọ kẹdogun oṣu yi.

Awọn enia mẹrin na ni wọnyi. Ọgbẹni J. S. Ọlawọyin, Ọgbẹni J. O. Lawanson, Ọgbẹni, J. O A. Akamọ ati Oloye S. T. Ọrẹdẹhin.

Gbogbo ile ẹjọ na lọ palọlọ ti gbogbo enia dẹ eti silẹ nigbati Ọlọla Adetokunbọ Ademọla. Olori, gbogbo awọn adajọ Agba fun orilẹ ede Naijiria nsọ ninu ile ẹjọ na lana.

Ọlọla Adetokunbọ Ademọla sọ pe, ohun ko ri ẹṣẹ kan ka si awọn enia mẹrẹrin na lọrun, nitoripe ko si ẹlẹri ti o fidi mulẹ pe nitootọ ni nwọn lọ si Ghana lọ kọ iṣẹ ogun, tabi nwọn gbimọpọ lati gbe Ogun ti Ọbabinrin Gẹẹsi ki nwọn si doju Apapọ Ijọba bolẹ.

O tun sọ siwaju ninu ọrọ pe, "Nitoripe, nko ri ẹsun kan ka mọ awọn enia na lẹṣẹ, mo gba pe, nwọn ko jẹbi ẹsun ti Ọlọpa fi kan wọn, nitorina mo da wọn silẹ ki nwọn maa lọ layọ ati alafia."

Orukọ awọn adajọ agba ti o ṣe ẹjọ na ni Ọlọla Louis Mbanefo Olori gbogbo awọn adajọ Ipinlẹ Ila Orun Naijiria, Ọlọla John Idomora Conrad Taylor, Ọlọla Veha Bairamian, Adajọ Agba ilu Eko, Ọlọla Lionel Brett ati Ọlọla Adetokunbọ Ademọla, Olori gbogbo awọn adajọ Agba orilẹ-ede Naijiria.

Orukọ awọn agbẹjọro ti o ṣe ẹjọ awọn enia na ni Thomas O. Kellock ati Ọgbẹni Olu Ayọọla.

Ọgbẹni Kellock lo ṣe ẹjọ Ọgbẹni Ọlawọyin ati Ọgbẹni Akamọ Ọgbẹni Olu. Ayọọla lo ṣe ẹjọ oloye S. T. Ọrẹdẹhin ati Ọgbẹni J. O. Lawanson (wo aworan rẹ ni oju ewe iwe kẹfa).

Siwaju eyi ninu ile ẹjọ na lana, ni Ọgbẹni Kellock ti ba iioko Igbimọ awọn adajọ marun na sọrọ lori ẹjọ awọn enia mẹta.

Awọn enia mẹta ti Ọgbẹni Kellock sọrọ lori wọn lana na ni ọgbẹni S. A. Onitiri, Sunday Ebietoma ati Ọgbẹni A. Okotiẹ-Yẹsin.

Ọgbẹni Kellock sọ fun ile ẹjọ pe, iwe alakọsilẹ arinrin ajo ti o wa ni idiroko ko ṣe alaye ju pe o fi awọn ti nlọ si idalẹ han bi nwọn ti nlọ ati bi nwọn ti mbọ.

O tun ṣe alaye pe, ko sọ pe gbogbo awọn ti o ba kọja lọ si Ghana, iṣẹ ogun ni nwọn lọ k , ko si le mọ ohun ti enia lọ ṣe ju wipe, ki o ma a sọ irinsi awọn arinrin ajo lọ.

Ademọla: "Ṣugbọn nwọn sọ ninu ẹjọ pe, Oloye Awolọwọ sọ pe, bi on ba ri aye sa sinu igbo nla kan, ni ori oke kan ni Ipinlẹ Ariwa, on le gbe ibẹ ma ju bombu oloro si ari ilu nipa bẹ, on le fi ipa gba akoso Ijọba.

Ọgbẹni Kellock ṣe alaye pe ko si ohun ti o jọ ọrọ na ninu ẹjọ ti awọn enia na ro silẹ. O si tun sọ pẹlu pe ko si ẹniti o lẹ ri ẹri kan gbamu ninu ọrọ na.

Siwaju eyi ni Ọgbẹni Kellock ti sọ fun ile ẹjọ pe, Ọgbẹni J. S, Ọlawọyin ko lọwọ ninu iditẹ si ẹnikẹni.

Nigbati Ọlawọyin gbọ wipe, Ijọba mba Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre ṣe ẹjọ ni O ba fi sare wa s'Eko.

O tun sọ siwaju pe, bi Ọlawọyin ti ṣe de Eko ti o si gbọ wipe Ẹnkuari Coker ti bẹrẹ ni awọn Ọlọpa ba lọ rẹgabu Ọlawọyin ti nwọn si sọ wipe o ngbero lati ditẹ si Apapọ Ijọba.

Ọgbẹni Kellock tun ṣe alaye pe, Ọgbẹni Ọlawọyin ko lọ si Ghana, ko kọ iṣẹ Ogun bẹ ni ko fi ipa ko awọn ohun ọṣẹ wọlu.

Ni ipari ọrọ rẹ, o wa rọ ile ẹjọ pe ki nwọn tete yara da Ọgbẹni Ọlawọyin ati Akamọ silẹ, nitoripe nwọn ko ni ẹṣẹ lọrun.

Bakanna ni o sọrọ pupọ lori ẹjọ Ọgbẹni Akamọ ti o si ṣe alaye pe alaiṣẹ enia ni Akamọ ti adajọ Ṣowẹmimọ ṣe idajọ ẹwọn fun.

Bakanna ẹwẹ ni Ọgbẹni Olu. Ayọọla ti o gbẹnuṣe fun Oloye Ọrẹdẹhin ati Ọgbẹni J. O. Lawanson. ọgbẹni Ayọọla ṣe alaye fun ile ẹjọ pe "adajọ ṣi ara rẹ lọna, o kọja iwọntunwọnsi" nitoripe Ọgbẹni Lawanson ati Oloye Ọrẹdẹhin ko ni ẹṣẹ kan ti enia ri ka si wọn lọrun.

Oniwe irohin wa kan ran wa leti pe, ni ọjọ kọkanla oṣu kẹsan ọdun ti o kọja yi ni adajọ ile ẹjọ giga, ọgbẹni G. S. Ṣowẹmimọ ṣe idajọ ẹwọn ọdun meji titi de ọdun mẹwa.

Ẹjọ ti awọn abanirojọ fun Ijọba ba wọn

Wọ OJU EWE KẸFA



J. S. Ọlawọyin



Ọlọla Ade, Ademọla Olori Awọn Adajọ



Ọgbẹni KELLOCK Agbẹjọro Ọlawọyin

# IWE SI OLOTU

## Mo Kan Saara Si Alakoso Apapọ Ijọba

Olotu inu mi y/o dun bi ẹ ba le gba mi ni aye lati kesi Olotu Ijọba Apapọ ilẹ Naijiria fun akitiyan ti o ṣe lori eto abajade enia kika to jade ninu oṣu keji ọdun yi. Inu wa si dun pupọ fun ipade ti Olotu Apapọ na pe awọn Olotu Ipinlẹ yio ku fun ijiroro nipa eto enia kika na.

Inu awa enia to wa ni Eko yio dun bi Olotu Ijọba Apapọ Ọlọla Alubakar ba le lo ipo rẹ rere lati pe Alaga Igbimọ Ijọba Ibilẹ Ilu Eko pẹlu awọn Olotu yio ku ati pe gẹgẹbi gbogbo si ti ṣe mọ pe gedegbe l'Eko wa, Eleyi yio dun mọ wa pupọ bi Olotu ba le ṣe eyi pẹlu.

Awa enia ilu Eko si tun gba Olotu Apapọ ni iyanju lati le tete jẹ ki nwọn ṣe eto ika enia na ki o tete ni iyanju sibi kan nitoripe eto ibo didi si ile igbimọ aṣofin apapọ si ti nsunmọ bayi ati pe ti nwọn ko ba ṣe eto enia kika yi sibi kan yio mu ibo didi lọwọ ilafara lewu o.

Modupẹ o olotu ọkọ ọba ko ni sa yio lẹsẹ o.

Emi ni
Payo Ogunkoya
EKO

## Awọn Alagbe Pọju L'eko

Inu mi yio dun pupọ bi olotu iwe Irohin Imọlẹ ba le gba mi laye lati ba awọn Ijọba Apapọ ati ti Ibilẹ Eko sapa nipa awọn alagbe ti ko jẹki a ri ile gbe ni gbogbo ọjọ, bi o wa ni ita nwọn ko ni jẹ enia gbadun rara.

O tilẹ ka awọn miran l a r a, wọn nwọle wa ba enia lati mọ se agbe wọn, bi enia ba duro, awọn alagbe yi ko ni ẹ ki enia gbadun rara'

Mo gbọ pe Ijọba Ibilẹ Eko ṣe ofin wipe ko ni si alagbe mọ rara, ṣugbọn ẹko ti mu ofin na ṣẹ rara ao gbọ nkankan nipa ọrọ na mọ rara

Ti alejo ba kọkọ wọ ilu Eko awọn alagbe yi ni nwọn yio kọkọ ri nwọn ko ni jẹ ki enia rin ni titi rara, bi enia ti nbọ lọwọ ọkan ni o tun nbọ sọwọ awọn miran.

Asiko to lati tun ilu Eko ṣe, a nfẹ ki ilu Eko mọ.

Olotu ẹ ku iṣẹ ajinde ara yio mọ jẹ o.

Emi ni
Rafiu,
Eko.

## A Dupẹ O

Olotu mi ọwọn, awa ara ilu Ẹpẹ dupẹ lọwọ yin gidigidi fun iranlọwọ ti ẹ ṣe fun wa lati le jẹ ki a tete ma ri iwe yin oloyinmọmọ ka lasiko. Awa ti sọ ireti nu pe Iwe iru eleyi ko le wa si ilu wa mọ nitoripe ni bi nkan ẹ mẹta ti iwe na ti wọ ilu Ẹpẹ awa ko ti ri iwe na mọ ṣugbọn pẹlu ayọ ni awa fi nra iwe na nigbati o de ilu Ẹpẹ lẹnu ọjọ mẹta sẹhin yi. Awa ara Ẹpẹ dupẹ lọwọ Olotu iwe na ati oṣiṣẹ lọpọlọpọ, Ọlọrun na yio ma ran yin lowo ninu iṣẹ yin.

Inu wa yio dun bi iwe yi ba le ma de owo wa nigba gbogbo gẹgẹbi a ṣe nri bayi. A si tun fẹ ki iwe na pọ si yio ma wa si Ẹpẹ

Emi ni
F. Olu. Ogunde
IBADAN

## Ijọmu nfẹ Iranlọwọ

Ẹdakun ẹ gba mi ni aye ninu iwe nyin oloyin mọmọ ti njade lojojumọ lati kesi Ijọba Ipinlẹ Ariwa ki wọn ki o le tete b a wa tun ilu Ijọmu ṣe ni aṣiko ti a wa yi; bẹ na ni a tun nbẹ Ijọba Ibilẹ Ilọrin ki awọn mọ gbagbe wa.

Gbogbo awọn o j u ọna wa ni ko dara mọ rara ti o si ti ba jẹ, agbara ti gbẹ koto sinu awọn oju ọna, ṣe ti o ba ni ọda ni koni ni tete gbẹ koto atipe, yio si rọrun fun awọn ti ntun oju ọna ṣe lati tete tun ṣe.

Atun nfẹ ile iwosan ni ilu Ijọmu nibiti ao mọ gbe alaisan lọ ti ko si ni ṣe wa ni wahala pupọ b i eyiti a nṣe lasiko yi. A fẹ irọrun fun awọn t i ngbe Ijọmu, a wa nfẹ mọ jẹ anfani ti awọn miran nje.

Eyiti o buru nibẹ ni ti ẹrọ omi t i ao ni ti a ṣ i kọwe titi ti o fi suwa. Omi ṣe pataki ninu awọn nkan ti a nlo, o m i ni a f i ṣe onjẹ, ni a nmu ni a t u n nfiwẹ pẹlu.

Inu wa y i o dun pupọ bi Ijọba Ibilẹ Ilorin a t i Ijọba Ipinlẹ Ariwa ba le da ọda si oju ọna wa ki nwọn tun fun wa ni omi ti ao mọ mu. Ni a s i k o ẹrun aki iri omi mu rara, anrin to ibusọ meta ki a to ri omi pọn, sibẹsibẹ omi na kiki eewu ni.

Olotu ẹ ku iṣẹ,

Emi ni,
M. A. Adifa
IJỌMU

## Iyipada Ile Iṣẹ

Eyi nilati kede fun awọn Onibara wa pe ati ko ile itaja wa kuro ni Ibadan patapata asi ti wa si Ilu Itirẹ ni Agbegbe Suru Lere ati Mushin.

Ẹnikẹni ti o ba fẹ bawa ra Iwe tabi Turari Ajẹbidan ki o wa si ile itaja wa ni Nọmba 1, Ishiba Street Odo Eran Itirẹ

## Apejuwe Ile Iṣẹ Wa

Ẹ Wọ Bọọsi ti o nlọ si Lawanson ni Yaba 3d pere ni ti oba sokalẹ ni Lawanson, bere Ilu Itirẹ. Ti o ba de Ilu Itirẹ bere ibiti nwọn ti npa malu, titi ibẹ ni itawe wa wa Ti o ba fẹ fi owo ransẹ fun ọja rẹ Adirẹsi mi niyi:-

Shoyinka
c/o Postal Agent,
Itirẹ Via,
Suru Lere, Yaba

AWỌN IWE TI O WA FUN TITA

| | |
|---|---|
| Iwe Egbogi Awo Igba Arun | 20/- |
| Iwe Egbogi Ajẹbidan | 25/- |
| Iwe Ala lati ọwọ Josẹfu Alala | 5/- |
| Itumọ Omi Ara ati Etutu | 20/- |
| Iwe Ilana Yanrin tite ati Etutu Ṣiṣe | |
| Iwe Afọsẹ Isẹdalẹ Yoruba ati psalmu Ajẹbidan | 4/- |
| Lilo ati Agbara psalmu | 7/- |
| Turari Iṣẹgun Ajẹ ati Adura Tete damilohun | 10/6 |
| Iwe Akọmọ Lesin Islam ati Orisirisi Iwe | 1/6 |

J.O. Shoyinka
c/o Postal Agenn
Itirẹ Via Suru Lere,
Yaba.
or 1,Ishiba Street (Odo Ẹran)
ITIRẸ

---

BERE OJULOWO EGBOI AWỌN FARANṢE TI NWỌN NPE NI - Eleyi yatọ patapata si awọn

**RICHẸLET**

Rọbi-rọbi. Iṣẹ rẹ lara enia ju da si fun Iwosan gbogbo Kokoro buburu ti o ba wa ninu ẸJẸ ARA' bi Mọnamọna,

FUN ARUN ẸJẸ ARA ENIA GBOGBO




Meji rẹ ko si ni gbogbo awọn Egogi ti nwọn npe ni TỌNIKI Ẹjẹ ti nwọn si ni kakiri ni owo pọọku adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di o w o Iyẹn ṣe ewọ, awa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npo ta ni lẹ yi,

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi ba wọn yẹn a ma a ba ojulowo egbogi atata ti a ransẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse ati ti awọn Tatambulu si Itali jẹ

Mọ daju pe, bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le se ọ, Lakuregbe, orisirisi Inarun, Oju ṣuṣu tabi didun, Jẹdijẹdi Akọ ba, arun Edọki, Aya - didun pupọ ati Ekuru laya.

Ara riro, lapalapa Egbogi-Amodi Apo ile ilọ, ẹhin didun tabi ibaradi riro pẹlu Egbogi RISALETI a ma a pa gbogbo kokoro buruku ti o wa nba ẹjẹ ara rẹ patapata yio si ni ẹjẹ rẹ mo tonitoni pẹlu.

Ṣa dan igo rẹ kan wo iwọ yio si ma a rohin rẹ fuu ẹlomina pẹlu

Bere Ṣọbu awọn:—
Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street ( Lagos.
Phone: 22878 Nigeria, Ọja Ita Faji)

# Awọn Ọmọ Ẹgbẹ Dẹmọ Jare Ẹjọ

AKURẸ:— Ni ile ejọ giga ti Akurẹ ni nwọn ti fi awọn en'a marun kan ti awọn Ọlọpa pe ni Ẹhanna ẹgbẹ Dẹmọ ti nwọn fi ẹsun ole jija ati iba nkan ẹnikeji ẹni jẹ kan. Nwọn si fi awọn ẹhanna wọnyi silẹ fun ọrọ ti agbẹjọro fun ijọba fi han pe ẹsun na ti nwọn fi kan wọn ko si ba ofin mu u. Adajọ ile ẹjọ na iya afin Oguntoye ṣọ pe on fi awọn ẹhanna na silẹ nipa iwe ti agbẹjọro na kọ Adajọ na.

Agbẹjọro na sọ ni ile ẹjọ pe awọn ẹhanna na ba awọn nkan ti owo rẹ si to adọrin pọnun ati pe nwọn si tun gbe pọnun mọkandinlọgbọn ti o jẹ ti Ọgbẹni Christopher Ogbue ati iya afin Ibilọla ni ọja Ereke-san ni Akurẹ ni ọjọ kẹrin oṣu kẹrin ọdun yi ni ọjọ ti Oloye S. L. Akintọla ati Oloye Fani-Kayọde wa fi ẹka ẹgbẹ Dẹmọ lelẹ ni ilu Akurẹ.

Awọn ọdaran marun na ni Dantiga Ifẹ, Inna Ifẹ, Abidoye Adeyẹba, Ibrahim Zaria ati Adu Ifẹ. Ẹ o si ri pe ninu ibẹrẹ ẹjọ na pe awọn ọdaran na jẹ mẹjọ ṣugbọn awọn mẹjọ si ti gba pe nwọn jẹbi ẹsun ti nwọn fi kan wọn, nwọn si ti sọ awọn mẹta na si ẹwọn oṣu mẹsan mẹsan pẹlu iṣẹ aṣe kara. Adajọ na si tun ni ki nwọn fun nwọn ni ọsẹ mẹfa mẹfa.

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 22-Feb 20) Edeaiyede yio sẹlẹ ni sakani ọdọ rẹ loni. Ṣugbọn nipa suru ati iforiti, iwọ yio bori, ọrọ nipa obinrin kan, yio fẹ da ija silẹ sọra.

PISCES (Feb 21-March 20) Maṣe jafara lati mu gbogbo ohun ti o gba lero ṣẹ, irọrun rẹ mbẹ niwaju, ija kan yio bẹ silẹ latin iwọ pẹlu aladugbo rẹ kan. Ṣọra fun aisan loni

ARIES (March 21-April 20) Iṣiyẹ meji wa fun ọ nipa ẹmi rẹ. ṣọra nitori awọn ojowu ki nwọn ma ba ṣe ọ ni jamba. Nṣe ni ki o lọ ni suru ati ifarada ki o le bọ ninu ewu na

TAURUS (April 21-May 20) Ọjọ oni dara fun gbogbo nkan rẹ, mase ba awọn to nifẹ rẹ lọkan ja rara. Ẹnikan nwa nfẹ iranlọwọ lati ọdọ rẹ wa.

GEMINI (May 21-June 21) Mase fi ara silẹ fun irẹwẹsi lati gba gbogbo ọkan rẹ, fi ọkan rẹ si ọna kan, gba imọran ẹniti o nfi ọna han ọ gbọ.

CANCER (June 22-July 23) Maṣe jafara lati ma gbọ ti ara rẹ, ọna kọna ti iranlọwọ ba gba yọju si ọ, ni ki o gba.

LEO (July 24-Aug 22) Gbogbo awọn oku ọrun lo nṣe alati lẹhin fun ọ nitori na mase jafara, gbogbo ohun ti o ba fẹ ṣe yara lọ se, ma ṣiṣẹ gbagbe awọn to yi ọ ka, alẹ ọjọ oni yio dara fun ọ nipa obinrin.

VIRGO (Aug 23-Sep 23) Iwọ yio gbọ irohin aladun kan loni, wa iranlọwọ awọn enia to bẹ ki nwọn ṣe ranlọwọ fun o, suru ni ki o mu, botilẹ jẹ pe lojojumọ ni nwọn na ọ nija maṣe ja.

LIBRA (Sept 24-Oct 23) Ero ti on gba lọwọ yio dara ṣọra ki o maṣe fi egungun ara rẹ ṣe ki omasi ṣe gbọn l gbọnju Ṣugbọn bi o ba ni suru ọjọ oni yio milijọ fun ọ

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) O dabi ẹni wipe iṣẹ ti a fun ọ ṣe mbi ọ ninu bi oba tilẹ jẹbẹ, oni lati ma ṣe eto tirẹ silẹ ki obirin ti iwọ pẹlu rẹ fẹ lọrọ pọ le gbadun re.

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 22) Alẹ ọjọ oni yio larinrin fun iwọ pẹlu obirin kan. ba obirin olobirin na ṣiri gbadun. Mase pe li ode oru ki nwọn ma ba fi jamba ṣe ọ paspa ara nfẹ itẹju.

CAPRICORN (Dec 22-Jan 21) Bi oba ni awọn ọmọde wẹwẹ lọdọ tọju wọn ki jamba kan ma ba ṣẹlẹ si sakani ọdọ wọn. Mase jeki ija ṣelẹ larin wọn.


BI O BA NI

**Iwe—Titẹ**

FUN

**Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orișiriș iwe itufọ tabi ijade Oku**

ATI

**Iwe gbeyawo**

TETE KỌWESI ILE—IṢẸ—ẸRỌ ITẸWE

**Modupẹ Printing Press**

16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985. Lagos.

KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO PỌKU NI A SI NGBA

IROHIN KO TO AFOJUBA

*Dan wa wo lẹẹanṣoṣo ki o ri iyatọ*



GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AY NIPA "DYNAMIREN" TỌNIKI

ALE-BI-ELE Egbogi Tọniki awọn Jamọnu titun ti gbogbo ara ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan iṣẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo.



Bi are ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala tabi iṣẹ ṣiṣe ti o ko le jẹun daradara, tabi ki o male sun daa da ọkun lọsan tabi loru tabi awọn iṣan ara rẹ gbogbo ki ṣe fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunlẹ daradarawọn iṣẹ tabi wahala ṣiṣe tabi fun awọn ailera gbogbo nyin ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja Ọgbọn ọdun lọ si ded'adọrin tabi jubẹ lọ. Mo dupẹ "DYNAMIREN' ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara di ọtun patapata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bẹ rẹ s'i dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kankan nigbakugba d'Arẹ" nigbakugba yio salọ pẹlu. Igbadun ati alafia yio de si ọ. Iyẹn daju. Bere Egbogi na ni Ṣọbu:-

Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street, Lagos.
ADEDUN CHEMIST
14. Wakeman Sreet, Yaba


## Ẹ ma Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumọ

